U.T.C.
DEPARTMENT STORE
SERVES
YOU
WELL

ELETI ỌFẸ
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fiwe yi ṣ e ikede si awọn Aṣoju iwe irohin Eleti Ọfẹ kakiri agbaiye wipe, enkeni ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ranṣẹ si wa, ao pe lẹjọ, ako si ni fi iwe irohin ranṣẹ si enibe mọ.

VOL. XI No. 631. LAGOS, SATURDAY, JULY 4,—JULY 10, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Gongo So, Sulu Gambari Je Oye Oba Ilorin

ILỌRIN. Ni gẹrẹ ti Abudu Kadiri, ọba ilu Ilọrin w'aja ni gbogbo awọn ọmọba ilu na ti bẹrẹ si rin sọtun-rin si osi. Awọn Balogun Ajikobi, Balogun Alanamu, Balogun Gambari ati Balogun Kara ti bẹrẹ si se ipade larin ara wọn lati mọ eniti o tọ lati fi jẹ oye ọba na, ti o si le mu ilu dani.

Ni atete-kọse awọn ọmọba ti a gbọ pe awọn ndu oye na ni Sedu Alao, Sulu Gambari, Arẹmu Isa, ati Alu Baba-agba. Gbogbo awọn ti a ka silẹ nwọnyi jẹ ọmọ-ọmọ nidile Abudu Salami.

Idile keji ti nwọn ti njẹ oye ọba ni Ilọrin ni idile Shitta. Awọn ọmọba ti o ndu oye mbẹ ni Alikali Oke Ọde, ati Bello Arẹmọ-Oye.

Alufa Alimi ni Fulani kan ti o fi ọgbọn alumọkọrọyi gba ilu kuro lọwọ Afọnja ọmọba Ọyọ ti o tẹ ilu Ilọrin do. Ki Alufa Alimi to ku, ọmọ meji lo bi si Ilọrin. Abudu Salami ati Shitta.

Iran ti Abudu Salami ti o ti joye ọba ni Ọba Abudu Salami, Ọba Suberu Mọmọ Ọba Ṣukulubi ati Ologbe Abudu Kadiri. Iran ti idile Shitta ni Ọba Aliyu, ati Sule.

A gbọ irohin wipe nigbati awọn Balogun mẹrẹrin fi ṣe igbimọ, nwọn gbagbe, nwọn ko pe Mọgaji Arẹ si nitoripe on na jẹ ọkan ninu ọmọba Ọyọ ti o ni ohun si yiyan ọba Ilọrin, afọbaje paapa lo nṣe.

Mọgaji Arẹ ranṣẹ sọ fun awọn Balogun mẹrẹrin wipe nitoto ni Erin mbẹ ninu igbo, ṣugbọn ko le da igbo ṣe, nitorina pipe ti nwọn ko pe on sinu igbimọ wọn, Sulu Gambari ti nwọn fẹ yan ni ọba on ko fi ara mọ rara.

Nigbẹhin, Sulu Gambari yi ni gbogbo ilu fi ara mọ wipe ki o jọba nitori ti o mọ iwe o si ti nṣiṣẹ ni abẹ ijọba ibilẹ, o si gbọ ede Oyinbo, on ni Ajẹlẹ fi ohun si wipe ki o jẹ oye ọba Ilọrin, on na ni nwọn si fi jọba.

Sulu jọba na rikiṣi pin.

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Througout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E.Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## Nwon Si Banki Ile Nigeria Pelu Pepa Owo Titun.

Ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ọjọ kini oṣu July, 1959, ni nwon ṣe awuye-wuye iṣile owo (Central Bank) titun ti ilẹ Nigeria ati owo ṣile kan pẹlu Pepa owo ti Nigeria titun ni nwon gbe jade. Ko si botiri ni ọjọ na jẹ nilu Eko.

Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ti iṣe Olotu Ijọba apapọse (Prime Minister), tilẹ Nigeria nilu Eko ni ẹniti o ṣi ile owo (Bank) na pẹlu ọrọ diẹ niba ṣoki wipe: Nipa siṣi ile owo (Bank) yi, adura mi ni ki ile owo na ati awon osiṣẹ inu rẹ ni ilọsiwaju rere, ki ile owo na si ma kun si,ki o jẹ iranlọwọ fun inawo ilẹ Nigeria.

Oloye Okotie-Eboh ti iṣe Alabojuto inawo ijọba apapọse, ti o jẹ ṣeranwo fun gbogbo enia nibi ayẹyẹ iṣile owo na sọ ninu ọrọ rẹ wipe:- Ile owo nla (Central Bank) ti ile Nigeria jẹ opo kan pataki ninu awon opo ti yio gbe ijọba ominira ti ao gba, lagbara Ọlorun, ni oṣu October, 1960, duro, ọrọ ti wipe bi ilẹ Nigeria ti nsunmọ ati gba ominira to yi, ile na koiti ni Ile owo tirẹ ti o jẹ pataki fun iṣẹ ominira ko tun waiye mọ.



OLOYE OKOTIE-EBOH

Oloye Okotie-Eboh tun tesiwaju pe, o je ohun idunnu pataki fun on wipe orukọ on yio ma wa titi pelu ọjọ kini oṣu July ti a ṣi Banki nla nilẹ Nigeria gegebi Alabojuto inawo ijọba ti on jẹ lasiko na. O ṣi dupe fun Ọgbẹni Cobbold, Olotu Banki nla tilu Oyinbo ati awon enia jankan-jankan ti nwon wa fi ọla won bukun isile owo na. o sọ wipe eyi fihan pe aye ti o ga ni awon ilu okere fi ilẹ Nigeria si.

Gomina agba, Ọlọla James Robertson, paapa tun fi adura si pelu: ki awon Olori Alufa marun to wa fi adura pari rẹ.

Alufa Archdeacon R. A. Ashley Dejo, (Asoju Bishop Anglican), Dokita J. T. Ayọrinde ti Ijọ Baptist, Alufa Jones, ti Methodist, Olori Alufa Leo Taylor ti Ijo Aguda ati Alfa Ibrahim, Olori awon Lemọmu ti Mọṣalasi nla nilu Eko.

## OKUNRIN KAN KU SI BALUWE MOSALASI ALAGBAYUN

EKO. A gbo irohin wipe, Okunrin kan fe we ninu Mosalasi Alagbayun, lojiji ni eyi gbe o subu lule o si ku, a koiti ri enia ti o mo oruko enia o ku na. A gbo pe eje lo bo Okunrin na ninu baluwe ti o ku si.

Okunrin kan ti oro na soju re so wipe, nigbati o de, o ba on ninu baluwe bi o ti bere lati yi omi si ori, be ni eje bere si da jade lenu re, ni on ba kigbe pe gbogbo enia wa wo, nwon bu omi fun ki o fi yonu, sugbon kowle lo o, eje si tun bere si san jade ni imu re.

Awon alase Mosalasi na gba enikeni ti o ba je ara ionma ibe laye lati sanra si ehinkule Mosalasi na, eyi ni okunrin ti o ku na fe se, ki olojo to de si i.

Nigbati irohin na de odo awon olopa, nabo oku omokunrin na lo sile alaisan fun ayewo lati mo kini ohun ti fa sababi iku ti o pa a.

## Ebi Ko Pa Imale Lo Ni on Ko Je Aaya

Nisisiyi okunrin Alufa kan ti o nje Sule se Alajapa lo si apa ona ile Ketu nibiti obo, a aya, lagido, ijimere ati awon edun gbe po yamura. On ni onje fun awon Awori, Egun ati egbado.

Alufa Sule koje je iru eran bayi, a si ma ba awon ti nwon ijio nse Alajapa kiri wi wipe, ko dara fun enia lati ma je obo.

Kakiri nibiti nwon ba de lasun, ni Alufa Sule ma nberei wipe obe kini nwon se, awon enia na a si dahun pe lagido ni, iru obe yi ni Alufa Sule ko je ti ena kan, eyi ko jeki Sule ni agbara fun irin ajo re ni tori ko ri onje je kanu.

Nigbati o se ti, nwon de ilu kan, ara Alufa Sule ko le nitori ko si onje ninu re. Nigbati ebi fe selese ni Alufa ni ki nwon fun on ni onje, nwon so fun wipe, obe obo ni nwon se. O dahun pe, ki nwon bu wa be, ni Alufa ba jeun yo ragbadu.

Eyi na lo pada di owe bayi wipe, nigbati ebi ko pa imale lo ni on ko je aaya, sugbon nigbati ebi pa Sule, o je obo.

## Ona Moto Lati Apapa Losi Oja Ojo

ABULE ADO. A gbo wipe Ijoba Iwo-Orun ti fi owo bi Oke meji Poun (£40,000) sina ile isura Badagry pe ki nwon fi egbaa medogun tun agbegbe Badagry ati Awori se, ki nwon fi egba marun la ona moto a ko gbo pa, a ko gbo mu nipa re mo.

Lehinna awon ara agbegbe Ojo si Apapa ko ara won jo, nwon si la oju ona moto lati Oja Ojo si Apapa lati gba na wa ni a ti nreti ki ijoba ba ni te ona na ki nwon si yo oda sori re fun wa.

Latigba na, ni awon moto onifaji, awon Bolekaja, ati awon Kit-Car ti nlo ona ti nwon koiti te na, nwon si ba gbogbo oju ona je, ti ko si atunse A fi eyi kesi Ijoba Iwo Orun ki o mase jeki ise awon enia na baje.

## Awon Adete Enia Nse Iyonu Nilu Lafia

LAFIA. Irohin kan kakiri wipe awon adete ti o wa ni igboro ilu Lafia a ma wahala awon enia ti o ba nkoja nipa titoro ebun tabi sise bara pelu tulasi

Malam Yusufu, Oba ilu Lafia se ikilo fun awon adete na wipe, ki nwon ye yo awon enia lenu. Oba si tun pase fun awon Olopa ibile wipe ki nwon ma f'oju si awon adete na eyikeyi ti o ba koja aye re ki Olopa ramu.

Nigbati awon adete gbo iru ikilo ti oba se fun won ati gegebi o ti de awon Olopa si won, nwon ko ara won jo, nwon si lo pariwo ni afin oba.

Oba bere lowo won pe, kini nwon fe? Nwon si dahun pe awon gbo ikilo ti oba se bawo ri oba tun se de awon olopa si won, oba ha nfe ki ebi pa won ku ni bi? Oba pase pe ki nwon jade kuro ni afin, nwon si nlo tiko-tiko ki nwon to jade.

## OWO OLOPA TE AJ'OMOGBE

EKO. Odomokunrin kan ti o nje Saka Akinyemi ti o nwa moto, ti o si ngbe Isale-Eko, ni a gbo wipe awon olopa ramu ti nwon si fisun esun wipe o lo ji awon omode meji gbe.

Oruko ti a gbo pe nwon npe awon omo meji na ni Adebisi Adeleye omo odun mejo abo, ekeji ni Kabiri Agunbinde, omo odun mesan abo. O ji awon omo na ko lojo 22nd asu June 1959.

Saka yi koiti soro niwaju adajo nitoripe awon olopa koiti fi ni orun sile, nwon nse wadi oro re siwaju.


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS :-

IKORODU TRADING COMPANY

20 & 28, Balogun Street, Lagos.

WỌ FUN IGBADUN

MADE IN NIGERIA

S.O.K

SINGILẸTI

ORISI MẸTA

ELIZABETH · S.O.K · Kamson

MADE IN NIGERIA · MADE IN NIGERIA · MADE IN NIGERIA

# Oloye Enahoro Se Adehun Television



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti o joko lọwọ osi ni Oloye Anthony Enahoro nigbati o mba awon igbimọ Britains Overseas Rediffusion Ltd. tọwọ bọ iwe adehun fun ẹrọ Television lati mu wa si agbegbe Iwọ-orun ni ilẹ Nigeria. Ẹniti o joko larin ni ọgbẹni Noel Sabine, Alaga igbimọ Ẹniti o joko lọwọ ọtun ni Sir Edwin Herbert.

## AFI FILA PA EKUN OJO KANSOSO NI IYI RE MO (APA .4)

Nigbati gbogbo awon enia gbo wipe omo Oloye Ojomu lo fi fila pa ekun na ati pe o si mbe lehin odi ni biti awon ode gbe nse etutu ti ekun ti nwon pa, gbogbo enia ṣi, nwon fori le ona lati fi oju je dodo ri ekunrin ti o fi fila pa ekun na, nwon si rose duro de lenu odi.

Gbogbo awon ode npatẹwo, nwon si nko orin bayi pe :-
O l'awo ẹkun, o l'awo ẹkun
Oloye Ọjomu l'awo ekun.

Bi awon ode ti nkorin yi, beni omo Ojomu njo larin won pelu fila ti o fi pa ekun na, gbogbo awon enia suru mo, nwon gbe korua nwon nko orin pe. —

Tani yio fara gbata. 2

Ekun ekun tani yio fara gbata.

Orin yi ni awon enia ko titi nwon fi gbe Afi fila pekun de ile oba. Gbogbo awon Onirara bere si ki i ni mesan-mewa.

Ninu kiki ti nwon n i b e ni awon gbogbo gbe ranti iru itu ti baba re fi fila na pa lasiko ogun nile Ondo. Gbogbo enia nro wa ki i niwaju oba nwon nta a lore, nwon si nye si

Bi a ba siro iye owo, ati duki a ti Afi-fila, pekuu gba ni ojo na, o fere to ogun oke poun. Koiti pari, e m a ka Eleti-Ọfe

## Salamotu Aniwura Ti Ri Oko Re.

OLOTU, Jowo gba mi laye lati funrere si eti gbo awon okawe re wipe, emi Salamotu Aniwura, ti mo kowe wipe, mo nfe oko ninu n i odun lati fi ye nyin wipe mo ti ri oko temi.

Eni na ni Tiamiyu Momoleso ti o ngbe N0. 73, Niger Street Kano. Nitori na mo be gbogbo enyin ti e se fita fita lati je oko mi, ki e fiyedenu.

Ketu ni ilu ti a bi ni si, o fere je wipe gbogbo awon enia mi lo je Aborisa sugbon emi ko fe ba won bo orisa. nitorina ni mo se sa wa si Eko lati polowo ara mi bi o tile je pe, o lodi si asa obinrin lati polowo ara re.

Idi re ti mo se gba ife fun Tiamiyu Momoleso ni wipe Alhaji ni, Alufa Alasiri ni, gegebi o ti je pe bi mo ba gba ife fun yio le gba mi kuro ninu gbogbo inunibini ti awon enia mi ba nse simi.

Nitorina, mo f e ki Tiamiyu Momoleso na bi o ba ri iwe mi gba, ki o wa si Eko, lati wa wa ba ni gbe fun osu kan ka si fi ebi ara wa han ara wa, lehin na ki o wa mura lati so yigi. Sugbon bi ina ko ba wo, ngo tun polowo ara mi.

## ỌLỌṢA MẸRIN PIN ẸWỌN ỌDUN MEJI-DIN-LADỌTA LARIN ARAWỌN

IBADAN. Ọlọpa sọ fun Adajọ wipe, n i n u o ṣ u February 1959, awọn Ọlọṣa mẹrin nwonyi wọ mọto akero kan ti o nlọ silu Eko lati adugbo kan ti nwọn pe ni Mọlete nilu Ibadan, nigbati mọto yi mbẹ lori ere ni awọn ọlọṣa mẹrin na fa ọbẹ yọ si dẹrẹba mọto na, nwọn ja a ju silẹ, nwọn si gbe mọto rẹ lọ pẹlu igba-din-mejọ apo koko ti o fi gbẹ.

Orukọ awọn Ọlọṣa na niwonyi (1) Lamidi Ayinde lọ si ẹ w ọ n ọdun mejila (2) Isiaka Kuṣimọ, ẹwọn ọdun mẹdogun (3) Ayọdele John ẹwọn ọdun merinla ati Taiwo Bello ẹwọn ọdun meje.

Baba k a u ati ọmọ rẹ obinrin ti o gba apo mọkanlelọgbọn dani ninu awọn apo Koko ti awọn ji na fi ara gba pelu. Adesina ni orukọ baba na, o wọ ẹ w ọ n ọdun merin, Wuraọla ni orukọ ọmọ re. adajọ n' ki o lọ san Igba Pọnun ko lọ ṣe agbẹjẹ mọd fun ọdun mej'. Bi ko ba si ri owo san ki o l[…] si ẹwọn ọdun meji.

Ọlọpa so fun adajọ pe awọn Ọlọṣa na ti nwọ ẹwọn ọjọ ti ṣe.

## Dr. Azikiwe Nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Dr. Nnamidi Azikiwe ti o jẹ Olori awon Oselu ni agbegbe Ila-Orun ile Nigeria. O sọ pe ẹrọ nipa ẹrọ Television logbe on wa silu oyinbo iye owo ti yio si na ijoba ki ẹro na to de ile Nigeria yio t o Ọkẹ medugbon ponun (£500,000).

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos. P. O Box 467

CABLES & TELEGRAM "ELETI - OFE LAGOS" Phone 23370

VOL. XI. NO. 631 SATURDAY JULY 4 - JULY 10, 1959


## Ma Se Niso Esan Mbo !

Gbolohun okole o k e wosika wa yi ni a fi se asayan oro wa fun enyin okawe wa l'ose yi, gege-bi iwa awa eda enia nile aiye wa yi, ti o je wipe eniti Olo[…]e ba ti gbe si ipo giga, yala ninu ile tabi nibi ise ko tun ni fe mo ti awon enia ti Olorun fi si abe abo tabi itoju re mo niwon igbati ohun gbogbo ba ti nlo deedee fun u.

O po ninu awon enia ti nwon je asiwaju, tabi akonije. Oga nibi ise tabi oluda'se sile tabi awon agbani-sise ti nwon ko je bere bi ehin omo elomiran ba le yo'ke iba ki tiwon sa ti wa ni otororo, oro ti buse. Ha ! ma se niso, esan mbo.

Oga tabi asiwaju miran koko, bi o ba se wipe Olorun gba laye de'bi wipe bi ko ba san'wo osu tabi owo ise awon ti o je mekunnu enia nse labe akoso re, kini-kan ko ni se, opolopo ninu awon enia ti nwon je olorire de aye ipo be ko ni bikita lati fi owo lo awon osise enia abe won. Ha ! ma se niso, esan mbo.

Awon miran tile wa ti nwon je eniti ori ti ba won se, ti nwon npe elegbe won ni ole; awon daju tobe ti nwon ko le se iranlowo fun enia elegbe won laiko ni gba adimowo, eniti nwon mo pe ko ri ise se, ti o nwa ise ni nwon yio tun gba owo lowo re pelu ileri lati fi wo ise, sugbon maalo-manbo, pabo ni, pelu owo jirimoyan ti awon na ngba l'osu. Ha ! Iwo se eyi ? ma se niso esan mbo.

Alagba, Olukoni kan ti wa nilu Eko wa yi ri, ti o je eniti o ti nko awon omo ilewe sugbon nigbati igbagbo esin re ko si lori, ko tun legbe arin ilu mo, o lo pago kekere kan sinu igbo ni Okun Alasia, lati ibe l'o ti ma nwa se wasu re nilu Eko, o ma nko orin bayi pe:-

Ere ese mbowa kikan-kikan

Ara Eko o, ere ese mbo wa kikan-kikan.




## Idahun Si Ibere Ebutemeta

Olotu,

Gba mi laye Olotu, lati fesi fun Okunrin kan ti o bere wipe, kini idi re ti nwon se npe Oyingbo ni Ebutemeta jeki nfun o ni ododo oro na.

Oke-odo ni oruko ti nwon pe e tele ri nigbati koiti si enikan ti o ngbe ibe. Sugbon oja kan wa ni Oke-odo na ti a npe ni Oyingbo, ibe ni awon Eko ati Egba Otta ati awon Awori ma npade ba ara won na oja.

Sugbon nigbati awon Oyinbo fe se kereni lati Otto si Oke-odo, nigbana ni nwon ti bere si pe e ni Abutment.

Abutment je ede Gesi, itumo re ni ede Yoruba ni Oke-odo, tabi odi keji odo. Oke-odo ni opo enia ti npe e latehin wa titi ki o to wa di odun 1920 nigbati awon Kiriyo ti o nse ise ni ogba reluwe so o Ebutemeta.

Titi di oni, awon npe e ni Oyingbo awon miran npe ni Oke-odo pelu, s'gbon ogunlogo enia lo npe ni E…tem…eta.

## OHUN TI AWON OMO WA LO KO NILU OYINBO NIWONYI

(O bere ninu iwe wa Ose to koja)

**Bacteriology** Ise eniti o mo iru ise ti egbogi nse lara enia.

**Anthropology**-Ise eniti o mo iyato larin ohun titun ati ohun atijo.

**Physiology**-Ise eniti o mo nipa okan ati ohun gbogbo ti o mbe ni igba aiya enia.

# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st July, 1959 to 31st December, 1959, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay, or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa Areas.

2 Tenders indicating a price per ton should be submitted in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP" and addressed to the under signed so as to reach him not later than Wednesday, 8th July, 1959. Late tenders will not be considered.

3 The successful tenderer will be required to remove, at his own expence, whatever scrap is available for sale (with the exception mentioned above) during the six month period indicated, within 7 days of the Authority's notification of such availability and will be required to make the necessary arrangements at his expense for all the scrap removed to be weighed in the presence of a representative of the Authority.

4 The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

A. R. CORDON
Secretary to the Authority

N. P. A. Notice No. 308
26th June, 1959

## Olori Awon Scout Joye Gomina Ile Tasmania



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Lord Rowallan K.T., K.B.E, M.C., T.D., Olori gbogbo awon Scout ti o mbe ni gbogbo agbaiye. On ni eniti Oba Obinrin ti gesi yan lati lo je oye Gomina ni ile Tasmania.

O ko eko re ni Eton College o lo si ogun 1914, o si tun lo si ogun 1939. O ti rin irin ajo lo kakiri agbaye o si ti de awon ilu bi Kanada West Africa, South Afrika, Malta, Gibraltar, East Afrika Japan, Amerika ati yika awon ilu Oyinbo.

## Olosa Fo Sobu Oyinbo U.A.C. nilu Kabba

KABBA. Irohin kan wa wipe awon olosa gbe ogun loja sobu oyinbo U.A.C. ni oganjo oru, nwon si gbe ile ifowopamosi (safe) ti a gbo wipe edegbeta ponun lo wa nibe nwon nwon si gbe idi siga Bicycle meji lo pelu.

Nigbati nwon de, nwon na ibon si asode ti o nso sobu na wipe ki o joko, ko si gbodo di de, beni ko gbodo soro. bi o ba si lanu peren, nwon o da ibon lu u ni agbari.

Titi ti nwon fi fo sobu na, isoju asode na ni, nigbati oro na de odo awon olopa, ni nwon wa ri afoku ile ifowopamosi (safe) na ni ari a meji. Owo ati ifon loju ona moto ti o lo si Benin. Nigbati nwon si ile owo na wo, nwon ba ponun meji dilogun ninu re.

Okunrin kan ti nwon npe ni Gogobiri ni owo olopa te, ti nwon si nse iwadi oro lenu re. Oro na wa nikawo awon olopa, awon nwadi lowo.

## OMO EGBE N.P.C. ILORIN PIN SI MEJI NITORI OYE OBA

ILORIN. Awon Omo egbe N. P. C. nilu Ilorin ti da si ona meji, lori eniti o ye ki o je oye Oba lehin Ologbe Abudu Kadiri, Oba Ilorin.

Apa kan ninu omo egbe N. P. C. gba ki nwon yan Malam Sulu Gambari awon apa keji taku wipe ndao! won ko f i ara mo, eniti awon fe ki o je arole ni Malam Alberi Bale Molete.

Sugbon awon ara ile Fagba kowe si Oyinbo Ajele agba wipe, nilu Ilorin idile meji lo nje oye Oba, idile Abudu Salami ati idile Shitta. Odi igba marun ti idile Abudu Salami ti je, ti idile Shitta Koiti je

Nitorina ki Ajele da gbogbo awon ti o ndu oye na duro ile Shitta lo kan.

Alkali ilu Igbaja ti kowe si Sardauna wipe, on gan ni oye to si nidile Shitta.

Bale Ba'a ati Lanwa ti nse fita -fita lodo awon Balogun mererin lati ri wipe on ni nwon yan si ori oye Oba.

Ajele agba ti kowe si Balogun Ajikobi, Balogun Gambari, Balogun Alanamu, ati Balogun Kara wipe, ki nwon fi ogungun otolo to oro na ki oro na ba si itaje sile, nitori pe on ko fe ogun tabi ote nigba ti ne.

## IWE SI JESU OYINGBO

OLOTU

Gba mi laye ninu iwe re lati ba Jesu 'Oyingbo soro die.

A gbo wipe o so fun awon ena pe agbara gbogbo laiye ati lorun ni a fi fun o, ati lati se awotan arun.

Bi o ba je wipe ni toto, ododo ni oro na, eni ti ko ri omo bi ko ha nse arun lo mbesa? Emi n o ogunlogo ninu awon ena ti o ti koja labe kunmo re, ti awon nitori wipe ki nwon le bimo ti nwon si lo wo ilo ti Jesu Oyingbo. Ki Jesu Oyingbo fi ye wa, o ha je pe gbogbo awon ti o nitori n w o n k o b i m o, ti awon si ti ow iju tire na l o h a ti bimo?

Emi ni
Lemomu Ajakuta.



## J[illegible] Oyingbo Tun G[illegible] Oro Re De !

EBUTEMETA. A gbọ irohin wipe ọmọkunrin Aladura kan ti o nje Emmanuel lo fun ara rẹ ni orukọ pe on ni Jesu Krist. Iye owo ti on nri kojọ larin edun kan a ma po to egbẹrun paun si ẹgba a. Ko nṣe awọn ọmọ egbẹ on lo nsanwo fun on, ṣugbon nwon nmu ore ọpẹ wa fun on, fun iṣẹ nla ti on nṣe fun won.

Jesu Oyingbo sọ wipe, ẹ gba mi gbọ, bi o ba je wipe o ni wora enia ni mi, o daju wipe emi ni yio je olowo ju loni.

Njẹ Jesu Oyingbo na ha ni ile isin bi ?

Nlao ! Awa ko ni ile isin, awa ni nwon npe ni egbe Alatunbi.

Bawo ni enia tiṣe le di ọmọ egbe Jesu Oyingbo ?

O digba ti mo ba na oluwa rẹ ni ẹgba mẹsan, nigba na ni iwọ yio gbagbe awon ebi rẹ ati ore rẹ, iwọ yio si ma tele mi lẹhin.

Gbogbo awon ọmọlẹhin mi ni mo ti na ni egba mẹsan mẹsan, ẹgba na ni yio je isami fun ọ pe, iwọ ti di ọkan ninu awon ọmọ lẹhin mi.

A ha ti so asọtẹlẹ wipe, nigbati Jesu yio ba pada de nigba keji, ilẹ Afrika ni yio ti jade ? Jesu hahun pe, awa jẹ ara awon Ju ti a ti fọnka. Ko di igba ti a ba ni wa sile Judia ki a to pe wa ni Ju. A ko sa le titori pe, a bi enia sinu oko lagbami okun ki a ma pe oluwa rẹ ni eja.

Nje a ha ti sọ asọtẹlẹ wipe, nigbati Jesu ba de nigba keji, yio ni awon elena bi ?

Jesu Oyingbo dahun pe, iyawo mẹje ni mo ni, sibẹ mo si ma je obinrin si.

Ki enia to gba olododo lo, o ni lati kẹkọ se bi awon olododo ti nṣe. Ṣugbon ni kẹhin ejọ emi ni kan ṣoṣo ni yio pada si na igo mi, mo ni lati gbeyawo ọpọ, nitoripe aguntan ni won je emi papa ni Olusọ-aguntan

## Ara Orun Kan Ku Lemeji

FIDITI. A gbọ irohin lati ilu Ọyọ wipe ninu oṣu May to kọja ni awọn egungun kan wọ mọto lati ilu Ọyọ nwọn mbọ ni Fiditi.

Bi ọkọ ti de Fiditi koiti duro tan bẹni egungun Alabala kan fo silẹ, o fẹ ṣe bi ọmọ ojẹka, ko fura wi pe aṣọ on ti kọ isọ. Fifo ti o fo silẹ, bẹni aṣọ tun fa a lẹsẹ, o si fi ipakọ lelẹ.

Ha, ha, ha, mọto pa egungun ni Garegi, ẹniti ko le rin ni ki a gbe on ati obinrin ati ọkunrin ilu Fiditi lo sare wa woran. Nigbati awọn Ojẹ ati awọn Atọkun ri pe t'awo-t'ogberi lo ti peju sidi mọto to se egungun lese. Nwọn ko mọ ohun ti nwọn le ṣe, Oyinbo Dokita kan ti o nkọja lọ si Ogbomọṣọ lo ri egungun na o ni ki nwon bọ aṣọ kuro lori rẹ.

Ibẹ ni Agan ti bẹ si meji gbo enia si tuka. Nigbati nwọn bọ aṣọ kuro lori egungun na, agbari rẹ ti fọ.

Bi a ba ti tun gbo oro na si ao jẹki ẹ gbo, nwon ni awon nṣe iwadi lowo.


Kere o !

A ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tọkunrin obinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos


## Okunrin Kan Subu O Si Ku

ILESHA. A gbo irohin wipe okunrin alagba kan ji ni owuro o si lo sodo Ọgbẹni Ezekiel lati ki i wipe o ku aro. A gbo wipe Ọgbẹni alagba na mura daradara, ko ṣe aisan rara ki o to jade kuro nile Ọkunrin na jẹ Onisọwọ.

Gẹrẹ ti o fi ṣọbu tirẹ silẹ ti o si fi ori le ọna Ṣọbu ti Ezekiel, lojiji oyi gbe o ṣubu lulẹ o ku patapata. Nigbati awon enia ma fi de ibẹ ẹjẹ bẹrẹ si yo lẹnu rẹ, o si nkan silẹ pẹlu. Nigbati o si ṣe diẹ gbogbo aṣọ ara rẹ ti rin fun ẹjẹ.

(Wo yoku loju ewe keje)

## Jamba Moto Sele Ni Gi..di Akwati

Lojo 19th osu June 1959 ni Mọto ti awọn Oyinbo (Cmpany Gindi Akwati) (exland) mbo wa lati ilu Yelwapẹlu Kusa pẹlu awọn Lebira ninu rẹ.

Nigbati o ku sata bi buso ki o de ilu Gindi Akwati bien oko moto na subu lule lati ori gada, o si ko ese mererin soke Enia meji lo ku bamubamu. Dereba moto na ati awon lebira ni nown gbe lo sile alaisan ni Barakin-Ladi nia meji ti a gbo pe Olọrun yọ won ninu jamba na ni Malam Gana ati Paul, Oluwa lo ni emi awọn ti o ku.

Orukọ Dẹrẹba na ni Ariyọ, oṣu rebete. Lọwọ ewu na, lọwọ ewu omi, ati lọwọ jamba mọto, ki Oluwa rere gba wa.

## IN LOVING MEMORY OF

My Loving Mother



Madam Selia Akonke

Buried 5th July 1950.

Sunre

Ma'mi Gbidinnibi

A. R. Amusa




AVAILABLE AT:-

AKOSHILE BROTHERS

5, BALOGUN STREET WEST.

P.O. BOX 599. LAGOS.

# Irun Odun Imale Nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn Musulumi enia to mbe nilu Oyinbo lasiko ọdun kekere ti nwọn lọ kirun ni adugbo kan ti a npe ni Woking nigboro ilu nla London.

Gbogbo wọn sujada fun Ọlọrun nigbati nwọn nkirun ọdun kekere (Id-Ul-Fitri) lẹhin awẹ. Awọn enia ilẹ Nigeria, Pakistan, Middle East ati Africa n i nwọn ba wọn kirun na Imam Khawaja Kamaru-deen ni o ṣiwaju kirun fun wọn.

# Ise Olopa Dun, K'arin, K'ama Yan



Awọn enia merin ti a nwo ti nwon duro niwaju oga olopa t i o mu opa dani (Wand) ni ara awọn enia ti nwon lo silu Oyinbo lati lo ko iṣẹ olopa fun ogunosẹ, ti nwon si ti yege. Awọn mejeji ti nwon duro ni apa osi jẹ ara ilẹ Nigeria, oruko won ni wonyi, Rigeto (Inspectors) S. Dimka C. Kaduru A. S. Taylor lati ilu Saro ati M'Boob ti ilu Gambia.

## Itan Afese Kan Pa Meje.

(APA 6)

Nigbati Afese pa Meje ti pari iṣe kini ti Ọba fun ṣe, oba na gbe iyin fun Afẹṣe pa meje wipe, o ṣẹ na lona ti o jọnlẹju gẹgẹbi ... re fi a ti si gbo, ... gba fun ... mi si balẹ wipe iwo ni yio ... ọmọ mi fe.

Nisisiyi iṣe keji ti iwọ yio ṣe fun mi niyi, ki nto le fi ọmọ mi fun ọ patapata.

Lẹhun ni, eranko buruku kan wa nibe ti o ni iwo kan ni iwaju ori re, a si ma fi iwo kansoso na se awọn e ia ni jamba. Inu mi yio dun jojo bi o ba tun le fi agbara nla re ba mi yanju ẹranko na.

Afese pa meji dahun wipe kai! o wire, ọba, ngo yanju rẹ kuro nisisiyi.

Ba mi wa aake kan ati okun kiakia, nwọn ti pese rẹ sile.

O mu okun ati aake na dani, lo ba te ori bọ igbo nigbati o de inu igbo, o duro, o fi ẹhinti, o si yọ fere kan lapo rẹ o bẹrẹ si ko orin bayi wipe.-

We le fiya, we le fiya,
We le fiya, je mi,
Laiye ọba

Nigbati ẹranko na gbo iro fere, o dide kian, o kori sibiti fere ti ndun, bi o ti ri Afẹṣẹ pa meje ti o fehin ti igi, o nsare bo wa lati fi wa lati fi iwo rẹ gun mo ara igi na, ṣugbon bi o ti kusata bẹni Afẹṣẹ pa meje yẹ ẹ, eranko na fi iwo gun igi na, o si wole. Lesẹkanna, o fi okun si lorun, o si fi aake ge iwo rẹ mo igi. O pada lo so fun oba pe ki nwon lọ yinbọn fun eranko ti ion muso.

Gbogbo ilu tun ho ge!

(Koiti pari)

OKUNRIN KAN SUBU O SI KU

(O bere lati ewe kefa)

... kan lo ba awọn enia alagba na nipa ohun ti o sele, gbogbo nwọn si dide nwọn wa ... re lọ. Bi nwon ti gbe oku na lo ... awọn ọlọpa ... nwon si lo ... oku na lo si ile Alaisan ijo Wesly Guild fun ayewo lati mo kini fa sababi iku ọkunrin alagba na.

Lẹhin wakati mefa, nwon da ku na pada wipe iku lati ọdọ Ọlorun lo de si okunrin na nwọn si gbe lo sin.

## Assistant General Manager E. C. N. Dies

The death occured early on Thursday morning of Mr Oladotun Coker, Assistant General Manager, E. C. N. Nigeria.

The deceased whose age was 50, who arrived recently from United Kingdom where he went on Post Graduate Course in Office Administration. He was educated at Kings College Lagos, before he proceeded to the U. S. A and United Kingdom where he qualified as Electrical Engineer.

He joined the P. W. D on his return from U. K and was transferred to the E. C. N. Nigeria, where he was promoted to the post of Assistant General Manager in 1959.

May his soul rest in peace.

## GOMINA AGBA YIO BẸ ILE LIBERIA WO

EKO. Irohin de etigbo wa wipe ile Liberia, ilu awọn Kurumọ ti ati gbọ wipe Gomina agba ati iyawo re yio lọ bẹwo ni ọjọ Jimọ ni yio di ọjọ Satide ọjọ Kerin osu July, ki nwọn to fi ile sile.

A tun gbo pe iyipada asiko na yio kan ilu Saro ti nwọn fẹ fi ẹsẹ kan bẹwo ni ọjọ kefa osu July si ọjọ kesan, yio di ọjọ keje osu July si ọjọ kewa. Lehinna ni Gomina agba yio lọ bẹ ilẹ Ghana wo ni ipari osu July, ni asiri, gẹgẹbi alejo Gomina agba ilẹ na, Ọlọla Listowel.

## Ibere Ati Idahun

(1) Ọkan ninu awọn ọmọ Akẹkọ isẹ agbẹ lo bere ọrọ yi lọdọ awọn Oyinbo Elepo mọto (Shell B.P.) wipe:-
Ile onilẹ, ti nwọn ba gba lati wa epo ninu rẹ, ti o si se ti nwon ko tun ni isẹ lati sẹ nibẹ mọ, bawo ni yio ti pe to, ki nwon to gbe ile fun onile?.
Idahun. Nigbana, ti isẹ wa ba ti tan nile na, ao tun ilẹ na se ao di gbogbo koto ti a ti wa, ao si se oju ile daradara fun nkan ọgbin ti nwọn ba gbin sibẹ, ao si da ilẹ pada fun onile.

(2) Nje awọn ọmọ ti a ba ti ko ni ẹko ninu ile ẹko ti Shell-B.P., bi nwọn ba pari ẹkọ wọn nibẹ tan, nwọn tun ni lati lọ si Yaba Higher College ki nwọn to pegede ni bi?.
Idahun. Ndao, Ọmọ ti a ba ti ko ninu ile ẹkọ wa ti o ba ti pegede, o pari nuni ko tun ni lọ sibomiran mọ. Odun mẹta ni a fi nkọ awọn ọmọ tiwa lẹkọ, yio lo ọdun kan ninu ile Ẹkọ, nwọn o wa lọ dan isẹ ọwọ wo.

## NEHRU GBA EBUN LATI KATHMANDU.

Eniti a nwo yi ni Prime-Minister Jawaharlal Nehru ti ile India. on ni a gbo wipe awon ara ilu kan ti nwon npe ni Kathmandu fi ere eranko ajanaku kan ta lore fun abewo re lo si ile Nepal.



JAWAHARLAL NEHRU


NI IRANTI IYA WA ỌWỌN

JANE LOKO

Eniti o dapọ mọ awọn mimọ ni ọjọ keji osu July, 1959
Sun're, Mamma wa,
Sun're.
Awa ọmọ rẹ.

"DE FACTO"
BREAD
THE BEST IN NIGERIA
MARKET
KNOWN FOR ITS NUTRITIVE QUALITY.

Lagos Race Club
AUGUST MEETING, 1959
Saturdays 1st, 8th, 15th, 22nd, and 29th August 1959
Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P. O. Box 51, Lagos or at the Race Course.
NOTE :- No Entry Fees will be refunded after the draw has been made. Entries close at noon on Thursday 9th July, 1959.

Plushes, Velvet, Velveteens, Damask
& Building Materials.
PLEASE CONSULT
Okunowo Brothers
63, Massey Street, (Faji Market)
LAGOS. NIGERIA.
The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed.

M.B.T
(MAGIC BLOOD TONIC)

Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú sàrà, ògì pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Àìsàn burúkú wọ̀gbà àìlèsùn rẹ̀hin-ẹ̀kùn. M.B.T. tògùn-ẹ̀jẹ̀ ti nmú ni jẹun bí ìkán, amú ni yágbẹ́ bí òkùn, amú ni tọ̀ bí ọ̀kẹ́rẹ́. Abiwẹ́rẹ́ fàbọyún, agbẹ̀jẹ̀ di fáwọn abiyamọ. Ahọ́n dúdú, ẹ̀ṣẹ̀ wíwú ati àiyà-jíjá ko si pẹ́nú nítò e. Ìjọ̀ pẹ̀lú ìfọ̀ owó-ọ̀kọ̀.
ARADAN STORES P.O.Box 2
EBUTE-METTA.


Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28 Kosọkọ Street P.O. Box 467 Lagos. Phone 23370